# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL I. NO 21. SATURDAY, DECEMBER 2, 1922. FOURPENCE.



*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.


## GBOHUN-GBOHUN.

### A TA 'GÒ K' ẸYIN APARÒ, OHUN OJÚ WÁ L' OJÚ NRÍ.

Ni *Monday* ọ̀sẹ yi, Adajọ kekere ti Kôtu awọn ọlọpa bu pọ́nwùn marun-marun *(£5)* ni sisan s' apo Ọba, fun ọpọlọpọ awọn obinrin Ṣẹkiri nwọn to ădọta ti a múwa siwaju rẹ̀ fun ẹ̀sun "kikọ́ ile *Bamboat.*"

### ỌRAN GBOGBO LORI ṢILE.

Ninu Iwe-irohin Ijọba ti *Thursday*, ọjọ kẹtale-logun oṣù ti o kọja, a ri i ka pe Ijọba bu pọ́nwùn mẹ̃dọgbọn-mẹ̃dọgbọn *(£25)* fun *Lawyer* ki *Lawyer* ni sisan, ki irufẹ *Lawyer* bẹ̃ tó le bẹ̀rẹ iṣẹ ṣiṣe ni ilẹ wa nibi: owó ti a ti ngbà ri ko ju pọ́nwùn mẹ́wa-mẹwa lọ (*£10*) fun *Lawyer* kọ̀kan: ọrẹ́ wa, ọgbẹni ADEDAPO KAYODE, oloyè B.A., LL.B. ti Ilu *Cambridge*, ẹniti o ṣẹ̀ṣẹ gba oyè *Lawyer* bọ̀ lati Ilu-ọba laipẹ yi, ni ko-nko owó-giga yi yio kọ́ rù!

### ỌRUN ALAKEJI A-RÈ IBỌ̀.

A bá awọn ẹbí ọgbẹni JOHN SANTOS ti o ti nṣiṣẹ ni Ganran nibi rí, ṣugbọn ti o wá di onișòwo ni Ibadan ni lọ̃lọ̃ yi, kẹdùn ikú rẹ̀ ti o ṣẹlẹ ni Ile-alarun Onikan *(Dr. Gray's Hospital)* ni *Wednesday* ọjọ kejile-logun oṣù ti o kọja.

### LADY CLIFFORD, AJIṢEFINNI

O dun ni lati gbọ́ pe ìiisan Ayaba wa tún pọ̀ si i tobẹ̃ ti o fi ni lati lọ si 'le ninu ọkọ̀ *Appam* ti o lọ nibi ni *Saturday* ọjọ kẹ̃dọgbọn oṣù ti o kọja. K' OLUWA ṣe e ni fifuyẹ́.

## Ẹ GBA WA O!

Awọn enia ti o ngbe Ita Porter ati ti Onikoyi ni Idunṣagbe kọ 'we si wa pe ita wọn nrùn pupọ fun omi-ẽri ti nwọn nda si i. A kesi oyinbo Oniṣegun Ilera kó má ṣai bojuto ọran yi fun awọn ara wa ni adugbo na, nipa ṣiṣe oju-àgbará diẹ sibẹ fun irufẹ omi-rirùn yi.

---

## MA FI TI Ẹ KỌ MI L' ỌRUN L' O DA F' ẼKAN ỌN OWU!!!

A ri iwe kan gbà lọwọ awọn ti nwọn ni nwọn jẹ ọmọ Adèlé ti nwọn si ni ki a tẹ ẹ sinu iwe-irohin yi: ṣugbọn gẹgẹ bi o ti jẹ pe awọn ti o kọ iwe na ko fi orukọ ati adugbo wọn si, "ọbọ̀lẹ" ki wọn fun ohun ti nwọn bẹ wa ni ṣiṣe na.

---

## EYI WŨN WA O.

O ta si ni leti fẹnrẹn wipe awọn Ijọ enia dudu mejeji ti Bẹtẹli ati Salem (*African Church Bethel and Salem Organisations*) ti fi ohun ṣọkan pọ nisisiyi, ati wipe bi Ọlọrun fẹ aṣelu ni nwọn o ṣe Ajọdun wọn kọkanle-logun l'oṣu ti o mbọ.

K' OLUWA m' ọjọ ro.

---

## PAGIDARI!!!

Ihin kan ni ninu *Wednesday* ọsẹ yi pe Adajọ Sir F. A. VENDER MEULEN ju Ọgbẹni JOHN OLAWUNMI GEORGE, Onidajọ "Kõtu" Ake, ni Abẹokuta, s' ẹwọn ọdun marun, ti yio fi sin 'ru fun Ọba, (*King*) fun jijẹbi ẹjọ ti a ba a ro, pe o gba owo jẹ nigbati o wa ninu ipo ẹlẹgẹ bayi.

A gbọ pe ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi, ni nkan yi ṣẹlẹ. Awọn *Lawyer* ti o "*hire*" fun ẹjọ na ni Ọgbẹni E. J. ALEX TAYLOR ati ADEBESIN FOLARIN.

A o tun sọ si ọrọ yi li ọsẹ ti o mbọ.

## OWÒ ATI ÌWA RERE KO NSABA RÌN PỌ̀.

Mo tuba o, ọgbẹni J. B. Majẹkodunmi otun gbogbo Ẹgba, olowo mo-fi-ṣe'lu-l'ore onipọnla-abiwapẹlẹ onile sa-ma-gbe'bẹ-ma-sauwo, oninure akọ-ma-si-ninu-awọn-onirikiṣi, ọta ẹniti-ko-f'ẹlẹgbẹfa-ru-ti-o-ngbe-elegbeje, ọrẹ ati oludamọran ẹniti-o-mọ-iwọn-ara-rẹ. Ọgbẹni mi ni owo abubutan o si ni iwa rere pẹlu—*What a great exception !!!*

Ki iṣe pe ko tun si awọn ẹlomiran ti o ni wabiwọsi owo ti nwọn si ni iwa rere pẹlu; ṣugbọn nwọn kere ni iye lọpọlọpọ. Nitori idanwo (*temptation*) ati ma tẹsi ọna buburu ti nini ohun alumọni aiye yi nmu wa ni o mu ki a sọ ninu Iwe Mimo (*Bible*) pe "O rọrun fun ibakasiẹ lati wọ inu oju abẹrẹ ju fun ọlọrọ lati wọ Ijọba ọrun lọ." O ṣoro ni, ki iṣe pe ko ṣeṣe. Iyato wa larin itumọ awọn ede oyinbo meji yi—*Difficulty* ati *Impossibility*. Ẹnyin olowo wa ni *Nigeria*, a bẹ nyin ẹ ma fi ifẹ nyin han si ilu nipa lilawọ si ohun ti o jẹ fun ire awọn olugbe rẹ. Nitotọ ni a sọ ninu Bibeli pe "owo ni gbongbo ẹṣẹ" ọna odi patapata ni ọpọlọpọ ngba gbolohun ọrọ yi si. Ki iṣe owo bikoṣe ifẹ owo ni gbongbo ẹṣẹ.

Ọrọ owo bẹ kọ. "Owo ko si enia kọ sian" owo ape-kanuko owo baba tẹnitẹni. Ki Ọlọrun jọwọ fun wa ni eyiti yio ṣe anfani fun wa o. Nigbati enia ni owo ti o si nlo si ọna ti o tọ, ẹkun ireti mbẹ. Ilọsiwaju awọn ọmọ wa ni *Nigeria* ninu ẹkọ nfẹ ọpọlọpọ owo. Awọn iwe irohin gbogbo bi Eko Akete ti o nfẹ ki a mọ ibiti abuku ilu wa, ki a ma ba fi ẹtẹ silẹ ki a si ma nọ lapalapa nfẹ iranlọwọ owo. Ituṅṣe ilu ni oriṣiriṣi ọna nfẹ ọgbọn ati owo. Nitotọ ni ode le nisisiyi, ṣugbọn ẹ ma jẹ ki a tan ara wa jẹ, nkan ma wa lọwọ awọn ti o ni o. Ẹ ma jẹ ki a ma pe "ko si ko si" nigbagbogbo ki "kosi" ma ba da wa lohun.

Ọlọrun ti o mu ode le ni sa yi, yio ṣare ilu asipada igba si rere ba olukuluku wa.

Ni oriṣiriṣi ọna ni ọgbẹni mi, ti mo juba rẹ ni ibẹrẹ ọrọ nii, ngba lati lo owo rẹ si ọna ti inu Ọlọrun ko ni ṣalaidun si. O jẹ iwa rẹ lati ma ran ọmọkọmọ ti o ba ri lọ si Ile-ẹkọ giga ti Abẹokuta ni inawo ara rẹ. Iranlọwọ rẹ fun Ijọ Abẹokuta papa ti Ikẹreku ko kere. Inawo rẹ lori Ile-isin ti Ikija ti a fi okuta kọ, le ni ẹgbẹrun ponwun *over £1,000* o wa lẹnu o mba Ijọ yi kanna kọ Ile-ẹkọ awọn ọmọde nisisiyi.

Iranlọwọ rẹ ninu nkan ti iṣe ti ilu—*agaga*. On li o ni ile ti Alufa Ijọ Ikereku, olukọ-agba ile-ẹkọ Ikereku ati eyiti olukọ-agba ile-ẹkọ Ikija ngbe.

Ti Alufa nikanṣoṣo ni o ngba owo diẹ kiun lori rẹ. Ogunlọgọ ile rẹ ni Mọkọla ni awọn Gambari ngbe l'ofẹ Akọ-ma-binu ni orukọ ti mo tun le fun ọgbẹni mi. Ọpọlọpọ ninu awọn ti o nṣiṣẹ labẹ rẹ ti sọ owo rẹ di Jẹ-ki-mbu-diẹ-nfi-gbọ-bukata. Sibẹsibẹ oju mẹnmẹn ati ẹmi ibakẹdun ko nje ki o da ṣeria fun iru awọn ẹni bẹ.

Ẹ jẹ ki a ma gbadura fun iru awọn enia bawọnyi pe ki nina ma tan owo wọn, ati pe ki awọn miran ti Ọlọrun fi owo jinki rẹ ti nwọn si nlo o si ọna pe bi-mo-ṣe, owo-lo-ma-jẹ, le tẹle apẹrẹ rere ti a fi ẹnu ba yi.

Ki Ọlọrun alanu, Ọba afẹnifẹre, Ọba ti mb'aṣiri Ọba ti nṣore funni ti ki isiregun, Ọba eleti gbaroye, Ọba ajọkẹ aiye, aṣakẹ ọrun, Olodumare aṣeyiowu, Ọba agbeni-madẹhun, Ẹniti ibukun Rẹ imu ni ila ti ki si fi lala pẹlu rẹ, Olufunni ni ohun rere gbogbo, jọwọ fi owo anfani jinki awa ti koi ti ni ati pe nigbati O ba funni tan ki a le ma lo si ọna ti yio wulo.

Igbein-Adun,
Abẹokuta.

## OPEN LETTERS No. 7.

To His Worship,
M. Greene Esq.,
Police Magistrate,
Police Court, Lagos.

Your Worship,

Please allow me to offer you the country's thanks for having given a condign punishment by imposing a £5 fine each, on those worthless, good-for-nothing and shameless Jekri women about 50 in number who were hauled before you on Monday last, by the police on a charge of keeping houses of ill-fame, or otherwise, behaving indecently in town.

Really, these women have by their incessant whoredom practically made themselves a nuisance to the community, and the wonder is, they are bold enough to carry on their nefarious trade, in spite of the very rigorous surveillance, to which they had been subject by the police department in time past, and of which we know.

However, I believe their experience on Monday in question, will doubtless serve as a deterrent to the continuation of surrendering their person for hire.

I raise my hat to your Worship,
Eko Akete.

## No. 8.

To His Honour,
A. R. Pennington, K.C.
Acting Chief Justice of Nigeria,
Lagos.

M'lud,

Very sorry to learn of your being laid up these three weeks; would your honour mind taking a sick leave of the Bench for a short sea-trip? think of this, "Old Uncle" as it will surely do you a world of good.

Eko Akete.

## No. 9.

To James T. Akiremi White Esq.,
Chairman, Parish Committee,
United Native African Church,
Phoenix Lane, Lagos.

Fidus Achates,

Really I am very proud of your present elevation in the church of your soil: your efforts in devising schemes for money with which to carry on the work of the school-church building now taken in hand are not unknown to me: may I cherish the hope of seeing you with a "Choker" in the near future, doing duty in your church, and thus follow in the footsteps of Papa?

Bravo!!!
Eko Akete.

## IGBẸ L' OWO WA.

### Ekuro.

Bi awọn oyinbo ile-ọwọ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọṣẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Idapọ-Owo (A. & E. T. A.) £11 10 fun *ton* kan
Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.) bakanna.
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores) do.
Miller do.

### Epo.

£21 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

### Cocoa.

Lati £25 de £28 fun *ton* kan bakanna.

## EKO AKETE·

Eko, Saturday December, 2, 1922.

———

### A LÈ GBE 'LE GB' ỌFA LAI R' OGUN?

Ọrọ yi li a sọ ni ọjọ diẹ sẹhin, nigbati a gbọ aroye pupọ lati ọdọ awọn aladugbo ti nwọn ngbe Opopo-nla, (*Broad Street*) ati Ita Campbell, (*Campbell Street*) fun òko ti a wipe awọn kan ma a nfẹran ati sọ si 'le wọn laiṣẹ-lairo, tobẹ̃ ti o fi jẹ pe a wa awọn oniṣẹ jamba yi tì: ti a ba wa 'di rẹ̀ ko le ju awọn ọmọ-ita lọ, ti nwọn nò ni iṣẹ meji ju ki nwọn ma a huwa aidara kakiri adugbo ni igboro: ninu awọn ọmọ-kọmọ yi èwẹ, li a nri ti nwọn jẹ oye tọwọ-bapo-tọwọ-bapo, eyi ti ẹnikẹni mọ ni "awọn ọmọ Jaguda."

A tilẹ sọ pe nigbati irufẹ iwa yi "gejia" enia tan, awọn aladugbo kan lọ fi ọran na han awọn Ọlọpa ni *St. Anna*, ṣugbọn a gbọ pe ko si ipa ti a ri sà fun wọn, nigbati o jẹ pe nwọn ko le ri awọn ti o nsọ òko na nigbati a wa nwọn: alẹ tabi ọsan-ganrin-ganrin ni awọn enia wọnyi nṣiṣẹ na gẹgẹ bi a ti sọ fun wa; òfo pupọ ni a si ti ṣe awọn aladugbo wọnyi lọna bayi, laika ọṣẹ́ ti nwọn ṣe awọn ti o wa ni 'le pẹlu.

A kẹ si awọn Ọlọpa wa, ki nwọn wa ọna ati da nkan yi duro nipa fifi awọn Ọlọpa-inu si adugbo-adugbo ti a gbọ pe iwa bẹ̀ wọpọ: boya nipa ṣiṣe bayi, ori ọkan ninu awọn ika-enia wọnyi le ta kò o, ti yio fi le jẹ ki awọn aladugbo "mọ ibi ti ibọn gbe ndun." bibẹ̃kọ, a woye pe iwa-ki-wa na ko ni dinku bọ̀rọ lọwọ awọn ọmọ eṣu yi, ti nwọn ya kẹtẹkẹtẹ-enia, nipa ika inu wọn.

A fi ọran yi kọ awọn Ọlọpa-inu ati awọn Ọlọpa-ode lọrun, a o si ma a wo "bírà" ti nwọn yio da si i.

A ko le gbe ile gb' ọfa lai r' ogun!!!

## KILOPO? No. 5.

LATI ỌWỌ, *EDITOR* EKO AKETE.

[A ko gbọdọ da Iwe yi tẹ lai gba'ṣẹ.]

———

### IṢẸ AKỌWE (*CLERK*).

Bi a ba bẽre lọwọ ọmọ-ile'we kan pe iṣẹ wo li o fẹ ṣe nigbati o ba jade? idahun ti a ro pe yio mu wa ko ni ju pe on yio ṣe akọwe lọ. A ko jẹ da irufẹ ọmọ bẹ̀ lẹbi, nitoripe gbogbo wa li a mọ gàlègalè awọn ọmọde lati ṣiṣẹ akọwe, kétè ti nwọn ba fi Ile'we silẹ, (awa nã pãpã sa ṣe ọmọde ri): Iro inu ọkan wa ni pe, ki iṣe iṣẹ akọwe nikan li o yẹ ki a mã nu ori ọmọde mọ, ogo ati iyi wà pupọ fun pe ki ọmọde kọ iṣẹ kan daju, lẹhin na, bi o ba fẹ, o le lọ dan iṣẹ akọwe wò.

Anfani ti o wa ninu eyi ni pe bi iṣẹ akọwe ko ba wọ̀ fun u mọ, o le lọ fọwọ mu iṣẹ ti o ti kọ, ti o si mọ daju lãrọ rẹ̀. Ãnu ṣe ni pe iṣẹ akọwe ṣa fun awọn ọmọ wa yio jẹ idiwọ fun wa lati kọ wọn bi a ti nni ẹmi ominira, eyini ni pe, ki a le da iṣẹ silẹ fun ara wa, ibãṣe siso-ọwọ-pọ lati mã ṣe iṣẹ kan, tabi wiwa ọna iṣẹ miran bi iṣẹ ọwọ (*industry*), tabi òwo, ti yio mu wa jẹ ẹni-ibu-ọla-fun lọdọ awọn oyinbo. Njẹ, nisisiyi, kili a ri? bi ayè iṣẹ akọwe kan ba ṣeṣi ṣi silẹ ni ibi iṣẹ Ọba (*Government*) tabi ni ile oyinbo oniṣowo, ki a to ṣẹju-pẹ, òjo iwe (*Application*) ati bọ sibi iṣẹ na ti yio rọ̀ si *Office* na ko ni kere: a tilẹ gbọ pe ni ibi iṣẹ miran, a nta ninu awọn akọwe ibẹ ni ipa nigbamiran, ni ohun ti a nri!!! kili o ro pe o mu eyi wa? nigbati gbogbo wa ba ṣi bi ẽṣú si iṣẹ akọwe nikan-ṣoṣo lai ronu pe iṣẹ miran mbẹ ti a lè fi ri onjẹ õjọ wa, ki a si gbọ bukata wa, ogo ni a nfi iwọsi bayi lọ̀ wa? Lati fihan pe iṣẹ akọwe ti di ohun ẹgbin, ọpọlọpọ ile awọn oyinbo oniṣowo ni mo ri ni ilu yi, ti nwọn kọ ọrọ wọnyi sibi ti gbogbo enia le rĩ ka ni ile òwo wọn, awọn ọrọ na li eyi.:—*No vacancy for clerks.*

itumọ rẹ̀ ni pe "Ko si aye fun awọn ti o nwa iṣẹ akọwe !!!" Ẹnyin ara, ẹ ko wa "ri imi ẹran ni idi enia" wayi? ni ijọ melo li a mã ṣe eyi gba? ni ijọ ti a ba le mu aṣeju a nlọ wa iṣẹ akọwe nikan lati ṣe kuro, nigbana ni a to le bẹ̀rẹ si sọ pe, a nmọ ohun ti a nṣe diẹ-diẹ bi orilẹ-ède.

---

## *Oran Ilu Nigeria No. 3.*

---

Aṣaro ti ọgbẹni HERBERT MACAULAY OLOYE C.E., ṣe lori ọrọ ti DR. JOHN RANDLE OLOYE M.B.,C.M. sọ ni Ilu oyinbo ti a tẹ si Iwe-irohin ti a npe ni West Africa ti ọjọ keji oṣu September, 1922.

Iwa ọgbọn ti awọn ọlọpa lo nipa ọran yi, awọn ti o jẹ pe a ti lu "agba nṣuna dan" fun lati lọ tu omi Ija si awọn janma lara nibiti nwọn gbe nsin Ọlọrun wọn, sọ idasi Balẹ ilu, Ogbẹni Henry Carr, M.A., B.C.L., d'asan, ko si fi aye silẹ ki a tun ri 'bi ma sọ pe ija ilu ni ki iṣe ti 'sin. Dr. Oriṣadipẹ Ọbasa ati ọga rẹ, Dr. John Randle mọ dajudaju pe Gomina kekere ti pari ija yi. Bi eyi ko ba si ri bẹ ẹ, ki nwọn wi-

Bi iwe-irohin *Nigerian Pioneer* ti nfi ojojumọ lu koro nipa lasingbo awọn Imale, ati pe iwa ti ọlọpa hu ko dara, nigbati nwọn nmu awọn ti o nyọnu ni Mọṣalaṣi, ti ikan tun ntọhun ni igbimọ Ọba pe awọn ọlọpa hu iwa ika si awọn mẹtalelogun ti nwọn mu nitori awọn janma Musulumi, bẹni Dr. Randle nke kikan ni adugbo ti nwọn ntẹ iwe-irohin ni London nipa ti rukerudo ti awọn Imale, ati pe loju t on ọrọ ilu ni nwọn nja si, ati pe awọn ọlọpa nfi iwe ipa mu awọn enia larin ilu,

Baba mi o, kili o sọ ọrọ yi di ti ilu, nigbawo ni "gbọn'mi si omi o to" ti o wa larin awọn Imale si di nkan ti a npe ni rukerudo ti awọn Imale. Nina esi ti Gomina agba ti si iwe iyẹsi ti ọgbẹni J. Egerton Shyngle ati awọn miran l'owọ si, ni ijọ kẹdogun oṣu *December, 1921*, Sir Hugh Clifford ṣe ilari pe "anyanjiyan" ti o wa larin awọn Imale Eko ti o si da aini ilẹ ara ẹni silẹ larin wọn, on o gbidanwo lati wa ọna kọna lati pari rẹ. Nigbati o si ti fi aṣẹ fun Gomina kekere, pẹlu iranlọwọ awọn oyinbo olori ọlọpa, nigbati Gomina kekere si ti pari rẹ pẹlu ifohun si Gomina agba, tobẹ ti awọn mejeji si jumọ nsin pọ ni mọṣalaṣi nla lati igbati Gomina kekere ti pari ọrọ yi, laiṣe ani-ani Sir Hugh Clifford ti mu ọrọ rẹ ṣẹ.

Ṣugbọn eyi ko tẹ Dr. Randle lọrun, ọkan ninu awọn Imale Eko ti sọ fun pe, awọn kan fẹ papọ nitori ati ri i pe Eleko pada si ipo rẹ ni.

Nigbati ọmọ enia ba fẹ ṣika,

Kiakia ni ọwọ won nto ohun elo buburu.

Ani Dr. Randle ko tilẹ sọrọ rere kan si iṣẹ ti Gomina kekere ṣe yi, nitori alafia ati ire Ijọba, eyiti o gori ẹmi awọn agabagebe wọnyi, ti a si tumọ fun wọn pe ifẹ ete lasan ni nwọn ni si Ijọba. O ha fẹ so pe on ko mọ pe Gomina kekere ti pari rẹ, abi ko tẹ ẹ lọrun lati ri pe awọn mejeji ti o ti njo sin lọtọtọ lati bi odun marun yi wa, Ijọba pa wọn pọ lalai gba imọran tirẹ ati ti awọn ẹgbẹ rẹ. "*Reform Club.*"

Ki nwon ṣa le ri bi ti bọ pe ija Ilu ni eyiti o wa larin awọn mejeji, ikan ninu awọn "ti o to oju abẹ sọ n'iko wọnyi" nfihan Ijọba pe nitori pe Lemọmu Buraimah duro ti Ijọba lasiko rogbodiyan owo-omi nitorina ni awọn jama ṣe iẹ yọ ọ.

Bẹni rogbodiyan ti owo-omi yi, awọn Dr. Randle Dr. Ọbasa ati awọn miran lo da a silẹ ni 1907, ti nwọn npe gbogbo ilu si ipade nigbakugba l' Ẹnu-Ọwa, ti nwọn si tẹ ẹ mọ awọn Imale ati Yoruba leti pe, "*Keria mi.*" A kọ ni san owo-omi nilẹ yi fun Ijọba, ti nwọn si ni ki nwọn ma lọ da owo wa lati fi ja ija ni, owo ti nwọn ri kojọ bayi lati fi ba Ijọba ja to ẹgbẹta tabi egbeje pọnwun. Nwọn wa l'ẹnu akatakiti yi fun iwọn ọdun mẹsan nigbati Lt. Colonel H C. Moorhouse adele Gomina kekere igbana kọ iwe bayi ṣọwọ si Dr. Ọbasa :—

No. L.C. 20/1915. "Nipa iwe ọgbẹni Boyle No. L.C., *20/1915*, ti ijọ kejidilogbọn oṣu *February*, 1910 ati eyiti o kọ ṣaju nipa ti iwe ẹbẹ lori sisan owo-omi eyiti akọwe-agba ni Ilu oyinbo ni ko ma jẹ ki on ri iru rẹ mo A ni ki nsọ fun ọ pe iwe ẹbẹ na jẹ ti ọjọ kejidilogun oṣu *November* 1915, eyiti o fi ranṣẹ si Gomina kekere ni ijọ kanna, ki iṣe ti ijo ogun oṣu *November* 1915, ti o si fi ranṣẹ ni ijọ kejidelogun oṣu *November* 1915, o dun mi diẹ pe a ko li eyi ye ọ dada.

2. Gomina agba ti ri esi gba si iwe ẹbẹ rẹ ti ijọ ogun oṣu *November* 1915, a si ni ki nsọ fun ọ pe akọwe agba ni Ilu oyinbo ni, ko lọ sagbejẹ mọ'di. K'on ma tun gb'ohun rẹ mọ n'idi a sanwo omi, ao sanwo omi."

Nigbati a ti ko eru eke le won lori, nipa pe lori owo omi ni janma ṣe nba Lemọmu ja, Dr. John Randle tun fi oruko titun fun ija Imale nitori a ti le ma ba ija yi lọ, o ni nitori ati fi Eleko si ipo rẹ ni nwọn ṣe dapọ.

Ki iṣe didun inu DR. RANDLE ki Lemọmu lọwọ ninu idapọ yi. Gẹgẹ bi Eleko si ti ṣẹ ẹ, o damọran pe aifayabalẹ yio ma wa larin awọn enia a fi bi Ijọba ba fi agbara fi alafia ati eto si ilu.

"Gbogbo enia sa lo jọ were loju asiwin."

## ỌRAN TI ELEKO ỌMỌ-ALADÉ.

Ogun ti g'oju Dr. John Randle nigbati o nba Aṣoju iwe irohin *West Africa* sọrọ yi. Oro ti o ni on lo fayọ ninu iwe ti awọn Aṣayan igbimọ lori Afrika ko, ninu ẹse kẹrin akiyesi ti Ọlọla Colonel Henry St. George ord, R.E., ẹniti a yan lati wadi ijoko awon ilu ti o wa labẹ Ijọba Gesi ni iwọ orun Afrika kọ ni ijọ kẹsan oṣu *March* 1865, ninu rẹ ni ọrọ na wa bayi :—

Dosunmu—Eko. Ni 1855, Akitoye w'aja, ọmọ rẹ Dosunmu si dipo rẹ. O jẹ enia ti ọgbọn rẹ ko pọ, ko si pẹ ki o to farahan pe ko to oye yi jẹ. ..... nitoto iwe adehun ti a ti kọ ṣe di fẹntuẹ, ẹnu lasan ni Dosunmu si fi npaṣẹ lori awọn enia rẹ.

Dr. Randle wa nsọ lọ.—"Bi eyi ba jẹ bẹ, mo gba pe iwe adehun ti a ton wa ṣe tọ, eyi si farahan ninu Ijọba atata ti a ni loni. Eleko ọmọ Baba rẹ ni, iwa ti a ko gba ni 1865, a ko le gba a loni." Lori ọrọ ti a kọ soke yi ni Dr. John Randle fi sọ pe adehun ti 1861, nipa eyiti Dosunmu fi fi ilu rẹ tọrẹ tọ, nitoripe ọgbọn rẹ ko pọ.

Ṣugbọn mo ro pe Dr. John Randle a ti ka ohun ti ngo fayọ lara iwe Colonel Ord. kanna yi kọ gẹgẹ bi emi na ti ka :—

29. "Iwe Dosunmu—Iwe ti Dosunmu kọ, ohun pataki ti o wa ninu rẹ ni pe, o ni owo ti a nsan fun on kere pupọ fun ilu on ti on gbe fun Ijọba. O ni owo ti on nri gba ni ilu on ri gẹgẹ bi owo bode lori Taba, owo eyọ ati nkan miran o to Ẹgba Pọnwun, laika owo ti a ngba lọwọ awọn ti o ba ru'fin, ati ọrẹ ti awọn oniṣowo nmuwa.

30. Ọpọlọpọ ẹri lo wa lati fi ri pe otọ wa ninu ọrọ Dosunmu niti pe Ẹgbẹrun Pọnwọn ko to iye owo ti o nri gba ki o to fi ilu rẹ tọrẹ, gẹgẹ bi ilana kẹta ninu ẹsẹ keji adehun na ti wi "iye owo ti o nwọle fun u lọdọdun o yẹ ki a yẹ ọran yi wo, bi a ba si ri pe otitọ mbẹ mbẹ, ki a fi kun owo ti a nsan fun lati ara owo ti Ijọba nri gba ni ilu.

33 Ako ọrọ kan ti o mu wa ti ko kọ si iwe, ṣugbọn ti Dosunmu mu wa si iwaju *Commissioner* ni pe :—Ọba miran ko ha ni jẹ lẹhin on, bi Ọba miran ba si ma jẹ, tani ma yan a, ati elo si ni owo ti yio ma gba.

Ọba mu ọrọ yi ni ọran ẹdun. O si yẹ ki a tẹ ẹ lorun, ki a si pari rẹ sibi kan, bi a ba fi ti si ibikan-aye ko ni si fun ẹnikọkan ni ijo miran lati tun ri ohun kan sọ si gbigba ti a gba ilu Eko lagbara."

Ki a wa bere, kini ohun pataki ti o mu Ijọba Gẹsi f'agbara ba adehun ijọ kini oṣu *January* 1852 jẹ, eyiti nwọn ṣe pẹlu Akitoye, ti o si mu wọn gba ilu Eko l'agbara niwọn wakati mẹrinlelogun ki Dosunmu to fi ọwọ s'iwe loju iọn awọn ọmọ-ogun ọkọ ogun.

Ọlọla John Russell, akọwe ilu ajeji ti ko si labẹ Gẹsi, ẹniti o jẹ pataki ninu ọrọ yi—ki iṣe Dr. John Randle—fi han gbogbo aiye ni ede Gẹsi ti o ye ni ṣakaṣaka ninu iwe ti o kọ ni ijọ kejilelogun oṣu *June* 1861, si *Consul Foote* ẹniti iṣe aṣoju Ijọba Gẹsi ni iha tiwa nihin.

Iwe pataki yi fi han gbangba pe a ko fi Dosunmu sun ẹsun kankan lati igba ti o ti rọpo Baba rẹ lati 1855, titi de 1861, pe o ba adehun ti a ba Baba rẹ ṣe jẹ, tabi ki a tilẹ da ni moran pe nitoripe ọgbọn ko pọ ki a gba ilu rẹ lọwọ rẹ. Kaka bẹ Ijọba Gẹsi ni ki a la a fun ohun ti o mu Ijọba Gẹsi ti o fi tẹ wa do si Eko, ki a si sọ fun Dosunmu pe :—

Ki iṣe pe iwa rẹ ko tẹ Ijọba Gẹsi lorun, ṣugbọn kaka bẹ a fẹ ba d'ọrẹ, ohun ti awọn si fẹ ni lati dabobo awọn ara Eko kuro lọwọ awọn ti nṣowo ẹru ati awọn ti nji enia ta, ti nwọn si nni ara ilu lara, a si fẹ lati dabobo ati lati fi idi owo mulẹ nitori bi Eko ti jẹ amu ilu, ki a si ma ti ipa bayi sọ awọn ilu ti o wa l'agbegbe rẹ d'ẹrọ fun irẹ awọn enia dudu." ( wo afikun B ).

Eyi ni ohun ti o mu awọn enia rere ilu Gesi fi te ilu Eko do ni 1861, ki iṣe nitori isokusọ eyiti Dr. John Randle enia dudu, lati ọpọlọpọ inu rere ọkan rẹ sọ pe nitori na "on ro pe adehun na dara pupọ."

O fẹrẹ mu ni ro pe Dr, Randle ko ka itan awọn Ọba lailai ati titun wo

A ṣọpẹ lọdọ Olorun pe Dr. John Randle ko mọ iẹba ti ọrọ wonyi bọ lẹnu rẹ bi ẹnipe a di ti o fi ṣe ijẹwọ yi pe :—

"Nko gba pe ede aiyede yi jẹ larin Eleko ati Ijọba nkan ni, ṣugbọn ede aiyede hanun ni arin Eleko ati awa ti—ti nwọn fẹ ti nwọn kọ—a ka si asọju ni ilu Eko,"

Nitotọ a wa ri ibi ti Ijangban ikan o j'ọkan ti a ti ndi si Eleko lati 1916, titi di isisiyi ti ndide.

Ki nwa bere "ti a nka si asọju ni ilu Eko," awọn wo ni nka yin si aṣiwaju? Ijọba ni, Gomina ni, tabi awọn enia dudu?

O to Ọdun mẹtadilọgọta nisisiyi, ko iti ju ọdun mẹta lo ti a fi ilu Eko tọrẹ, awọn obilẹjẹ bi awọn ti isisiyi ko enia lọ si ile Gomina, nwọn lọ sọ fun pe, Ọba Dosunmu ati awọn Ijoye Onifila-funfun nyọ nitori nwọn gbọ pe Ijọba Gẹsi fẹ fi Eko silẹ, ati Gomina ati awọn Ọmọ-ogun gbogbo wọn ni yio lọ yanyan. Gomina Glover ko gba iwikuwi ti nwọn wa dimọ Dosunmu gbọ, o ni ki a ṣe ikede kan sode eyiti o pana isọkusọ awọn enia wọnyi l'oku. Ni ọdun 1891, o to oṣu mejila ti Ijọba Gẹsi ti fi ilu Heligoland fun Ijọba Jamani, mo wa ni ilu Oyinbo nigbati iwe irohin *The North British Daily Mail* ti ijọ kẹrinla oṣu *Decembe 1891*, sọ pe Lord Salisbury nfẹ gbe ilu Eko fun *France*, ṣugbọn ina ko wọ.

Ni ọdun mẹrinlelogoji ọhun, bi a ti ri ede aiyede hanun larin Oba Dosunmu ati awọn ẹgbẹ ọtọkulu kan, bẹna ni a ri awọn ti o jẹ obilẹjẹ igbana nisisiyi awọn ti npe'ra nwọn ni nkan gunmọ, awọn ti nwọn nlo ọgbọn alumọkọroyi, lati wa ọran fun awọn ti nwọn ba korira, ti nwọn si ni ayọ ninu a ngbẹsan, iru iwa kanna ti adota ọdun ọhun on lo tun yọ ninu ẹgbẹ "t'ọlọmọ kan lo ṣuro" *Nigeria*.

Ni oṣu *May 1878*, awọn lamudọgi kan sọ fun Ọba Dosunmu pe Adele Gomina nfẹ ṣe ofin kan lati mu ilana keji ti adehun 1861 kuro, eyiti o sọ bayi pe "A o fun Ọba Dosunmu laye ati lo ipo Ọba lọna ti enia dudu nitoripe akẹtẹ koroba ti ade wa niwaju rẹ eyiti Ọba Dosunmu nde, nbi adele Gomina ninu.

Kiakia ni Ọba Dosumu bẹ BISHOP CROWTHER pe ki o ba on ri Gomina lati mọ bi otitọ ni, Gomina si fi BISHOP CROTHER lọkan balẹ pe irọ patapata ni, o si kọ iwe si Ọba Dosunmu, o fi ran BISHOP na pe, ko si otitọ ninu rẹ, ati pe bi akẹtẹ koroba ba ti rọ ẹnikẹni lọrun, o le ma de, ko si t'on ninu iyẹn. O si ranṣẹ pe Ọba Dosunmu lati wa ba on ṣe ariya, nwọn si jọ ya aworan pọ ni ẹsẹ ti o kọju si ebute ẹhingbẹti, Gomina MACOLM JANSON BROWN duro gbangba l'ẹgbẹ rẹ, Ọba Dosunmu si de akẹtẹ koroba rẹ pẹlu ade ni iwaju. Ọkan ninu aworan yi wa ni ile Gomina l' Eko d'oni ol'oni.

---


## CLIMAX.

World's wonder hair beautifier for men only.

Will straighten the most stubborn, coarse, or kinky hair in five minutes, make hair lustre and silky, without the least bit grease, absolutely harmless.

Sophia's cream brown Pomade known as a national hair remedy which feeds, nourishes and beautifies the hair, will eradicate dandruff, grow your hair long, lustrous, soft and fluffy for women and men; Also assorted kinds of pomade and toilet soap in stock.

DIPO TUNDE, & Co.,

P. O. Box 335,
37, Ajiṣomo Street,
Lagos, Nigeria.

## Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER.

OYINBO GERMAN ONIṢOWO NI HAMBURG

fẹ ka sọ fun nyin pe ẹ le wa wo oriṣiriṣi irepe ọja pẹlu iwe-ọja on ni.
Ile-Owo rẹ *No. 7*, Ita Labinjọ,
leti Ita William l' Eko.

Yi o tete bajuto iwe ti ẹ ba kọ si i, ti ẹ ba si fi sinu apoti iwe rẹ No. 459, ni ile-ipinwe t'Eko, ati iwe-ti ọja ti enia ba fẹ ranṣẹ lọdọ rẹ. O yẹ ki awọn onibara rẹ tete wa ranṣẹ ọja wọn fun akoko oṣu Awẹ ki o ba le tete de: oniruru ọja lo le ranṣẹ fun ẹnikẹni, o si ni ọgọrọ ọja loriṣiriṣi.
Ẹ wa wo o!!!

## CHANGE OF NAME.

From SAMUEL AIYELẸṢỌ FAULKNER
To AIYELẸṢỌ ỌLARINDE

Expert Repairer of Cycles of different makes, Sewing machines, Musical Instruments.
etc., etc., etc.
Come for a trial.
Workshop; 21, Williams Street, Lagos.

## BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni "MAGARINE"

Ọlọja Agba Ayinrin

ti gbogbo enia nsure si, wa fun tita ni Ile awọn Oyinbo Oniṣowo,

STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.
Ni Ibode lailai (Custom Street) L'Eko

Ṣile kan pere ni pann kọkan; o ṣe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to Iyẹpẹ, ṣugbọn bẹ lo si ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara nja ọ.

Are you impotent suffering from sexual nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man In short it will rejuvelate you, also unsurpassed remedy for female Neulasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

VIDAL. R. COLE

"Ajenifuja" Store
P. O. Box 201
109 Broad Street Lagos.

## *Preachers for To-morrow.*

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. ( Morning )

Masses Isin Arọ,

6.30—7.30 8.30—8.30
7.30—8.30 9.30—10.30.

( Evening.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ANGLICAN

Time. Preacher.

9 a.m.—Christ Church Rev. M. S. Cole
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. & 6.30 p.m.—St. Paul's ( Breadfruit ) Ven Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
9 a.m.—St. John's (Arọlọya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do do
9 a.m. & 4 p.m.—St. Peter's (Alapako) Rev. J. A. Cole
9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity ( Ebute Ero ) Rev. S. J. Gansallo.
9 a.m.—St. David's (Jordan) Rev. J. A. Leigh

WESLEYAN

10.30 a.m.—Tinubu Rev. A. N. Cole
7 p.m. Rev. S. A. Pearce
10.30 a.m.—Ereko Rev. E. K. Ajai-Ajagbe
7 p.m. „ J. C. Cole
10.30 a.m.—Olowogbowo Rev. E. E. Williams
7 p.m. „ A. N. Cole
10.30 a.m.—Ọbun Eko Rev. D. A. Beckley
7 p.m. Bro. Samuel O. Taiwo

AFRICAN (COMMUNION)

9 a.m.—Jehovah Shalom Rev. M. B. Newton
7 p.m. Bro. J. T. A. White
9 a.m.—Erelu Bro. J. H. Lawson
4 p.m. do do
9 a.m.—Bethel Rev. H. Atundaolu
6.30 p.m. „ E. A. Akiọla
10.30 a.m.-African Methodist Bro. W. K. Fafunwa
4.30 p.m. „ J. A. Oshodi
9 a.m.—Ararọmi Church Bro. E. A. Ojo
4 p.m. Rev. A. A. Puddicombe

EBENEZER

9 a.m. Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m. Bro. M. D. Adegboye

St. STEPHEN'S (EPETEDO.)

9. a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

BROTHERHOOD.

7.30 a.m.—Ilupesi Bro. O. S. Olukọya Ọnabanjọ ( Olori Ijọ Brotherhood ti Ijẹbu-Ode )
7 p.m. „ Pastor. A. Adedeji Iṣọla

AHMADIA.

5.30 p.m.—Open Air Service Prof. A. R. Nayyar ( Luther Street.)

COLONIAL CHURCH (ODAN)

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

## Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!

Owo Iranlowo ti a ṣi ri gba ni wọnyi.

| | £ s d. |
|---|---|
| Owo ti a ti ri gba | 9 19 0 |
| Ọgbẹni O. T. Ṣomẹfun on a/c | 0 5 3 |
| Aropọ | £10 4 3 |

Ara ilu, Ẹ jare Ẹ ma jẹ ko rẹ nyin.

A o ma jihin yi lọsọsẹ.—[Ed.—E. A.]


Don't wait the moment of need!

Provide for the time of Emergency!!

The Nigeria Labour Corporation is established as a " City of Refuge " for all classes of work-people, and is open to all to come and join.

It is the only independent organization protecting the interest of all its members in points of business in all parts of Nigeria.

If you are unjustly treated by your employers, the Corporation will fight freely for you to secure your Right.

If you are out of employment, the Corporation will assist you to obtain employment.

Make no hesitation, insure your business interest by becoming a member.

THE NIGERIA LABOUR CORPORATION,

Write for terms (enclose stamp for reply) to

51 Palm Church Street, Lagos Nigeria.



Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o si " Ṣabu" Egbogi Oyinb si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Willias Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina l' Eko.

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lona iṣẹ re.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8 30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo.

Ogun rẹ jire.

## ASHTON KINDER & Co.

A ṣẹṣẹ ni Agba *Cement* ti o dabi Okuta-inu Omi fun tita ni ile Owo wa.

Ni Opopo-nla No. Lọ bere nibẹ.

JAMES A. DISU,
Aṣoju (*Agent*)

---

## "O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

### N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

## J. F. SICK ati Awọn Egbẹ.

No. 7, Ita Ibode bilai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAṢINI-ARANṢO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo won han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAṢINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, Nwọn si nranşẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AṢIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

---

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

---

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Şẹda, Onini, Owu-Şẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ (*Felt*) Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita 'ti owo wọn ko ta enia lafya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kõtu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

### ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba à sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Oja Shefield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-oyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ILE EGBOGI IṢẸ OLODUMARE.

---

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni, Işẹ Olodumare si oja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orififọ, Inurirun, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.
Iwọ ko tilẹ gbọ orukọ rẹ ndan?
Işẹ Olodumare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

---

### F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo oniṣowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ loriṣirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JOJO ni oniruru to tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'Eko.

---

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Maçaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko.

Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

---

AWON ẸGBE OYINBO ONIṢOWO TI A NPE NI

### E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn oniṣowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranṣẹ ọja fun enikẹni to ba fẹ' ibaṣe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranṣẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L' Eko.

Enikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo oniṣowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin l'ede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?
Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi tọ wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.